# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ̀

## BIRIKI LÁÌSÍ KORÍKO

## Ìtàn ...

**Eksodu 4:29-5:19**

Síwájú kí Mose tó lọ ko ojú ọba Egipti lati gba ààyè fún ominira awọn ọmọ Isreali, oun ati arakunrin rẹ Aaroni kọ́kọ́ lọ ba awọn akonisiṣẹ olórí Isreali. Nibi tí wọn ti nṣe ìpàdé náà, Mose ati Aaroni gba awọn ọmọ Isreali níyànjú pé ki wọn ya ara wọn si mímọ́ fun Oluwa, bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú pé Ọlọrun ti ṣetan lati yọ wọn kúrò ní oko ẹrú pẹ̀lú ọwọ agbara nlá.

Awọn ọmọ Isreali ti nse iṣẹ fun ọjọ́ meje ni ọsẹ̀ ki wọn ki o le tèsíwájú ninu ìṣìn lile wọn fun Egipti. Sùgbọ́n, lẹyin tí wọn ti pari ìpàdé, wọn pinnu lati ma a sinmi ni ọjọ keje. Nítori ìdí èyí ni Faraoh se binu wí fún Mose ati Aaroni wípé: ‘‘ẹnyin si mu wọn sinmi kúrò ninu iṣẹ wọn.’’ Eksodu 5:5. (Ni èdè Heberu ìtumọ "Isinmi" ti wọn lo nihin ni "ọJọ isinmi". Ki wọn ko le e pa a mọ́.



Ọba ro ni ibinu rẹ pé oun gbọdọ ṣe ohun kan ní kíákíá lati mu awọn orile náà mọlẹ labẹ isinru ijọba rẹ, o pinnu rẹ pe, oun yíò fun wọn ni iṣẹ de ibi wípé wọn kò ni le rójú sin Ọlọrun mọ́. O wípé, "Ẹnyin kò gbọdọ fun awọn ènìyàn yii ni koriko lati se biriki bi ìgbà atẹhinwá: jẹ ki nwọn ki o ma lọ sa koriko funrara wọn. Ati iye biriki ti nwọn ti ima se ni ìgbà atẹhinwa, ni ki ẹnyin bù fun wọn; ẹnyin ko gbọdọ mú kúrò nibẹ." Eksodu 5:7,8.

Bi ìgbà ayé Mose, Ọlọrun fẹ́ se ohun nla fun awọn ènìyàn Rẹ̀. Iàìpẹ wọn yio bọ́ lọwọ ẹrú ẹ̀ṣẹ̀, wọn yio si rin irin ajo lọ si Kenaani ti ọrun. Lẹẹkan si, Ọlọrun fẹ́ lati da ọkan awọn ènìyàn pada sinu pàtàkì isin ti ọjọ isinmi.

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọ̀ọkan tán.

**1.** Nje Isreali nikan ni Ọlọrun dá ọjọ isinmi fún?
**Marku 2:27**
O sì wí fun wọn pé, A _______ ọjọ isinmi nitori _______, a kò da ènìyàn nítori ọjọ isinmi.

Àkìyèsí: Nígbàtí Jesu sọ wipe A da ọjọ isinmi nitori ènìyàn, ọ̀rọ̀ náà ‘‘ènìyànọ̀ọ túmọ̀ sí “gbogbo ènìyàn’’ ati fun gbogbo ìgbà ni ibi gbogbo.

**2.** Nígbàwo ni Ọlọrun dá ọjọ isinmi?
**Genesisi 2:1,3**
BẸ́Ẹ̀ li a _______ ọrun oun ayé, ati gbogbo ogun wọn, Ọlọrun si busi ijọ keje, o si ya a si mímọ́; nitori pé, nínú rẹ̀ li o sinmi kúrò nínú iṣẹ rẹ gbogbo ti o ti bẹ̀rẹ̀ si iṣẹ́.

Àkíyèsí: A dá ọjọ isinmi ni opin ọsẹ ti a ti da ohun gbogbo.

**3.** Ọjọ́ wo ninu ọsẹ̀ ni ọjọ́ isinmi?
**Genesisi 2:2,3**
Ní _______ _______ Ọlọrun si parí iṣẹ rẹ̀ tí o ti nṣe; o sì sinmi ní _______ _______ kúrò ninu iṣẹ́ rẹ gbogbo ti o ti nse, Ọlọrun si busi _______ _______, o si ya a si mímọ́, nitori pe, ninu rẹ li o sinmi kúrò ninu iṣẹ rẹ gbogbo ti o ti bẹ̀rẹ̀ si iṣe.

Àkíyèsí: Ní ìgbà mẹta ninu Genesisi ori keji, ni Ọlọrun sọ fun wa wipe Oun dá ọjọ isinmi ní ijọ keje ọsẹ. O sì yà á sí ‘mímọ́’, èyí túmọ̀ sí wípé ‘a yà á sọ́tọ̀ fun ìlò mímọ́‘. Ọlọrun se ọjọ isinmi náà ni wakati mẹrinlelogun, nitori lati ni ibaṣepọ to dara pẹlú Jesu, a ri wipe o ma n gba àkókò. Èsù gẹ́gẹ́ bi i Faraoh ti Egipti, o fẹ́ ki a ma siṣẹ ni gbogbo ìgbà títí ti a o fi gbagbe Ọlọrun. O ti mọ̀ wípé awọn ènìyàn kò ni ri ààyè, Ọlọrun ya wákàtí mẹrinlelogun sọ́tọ̀ lati ma a ni ajọṣepọ̀ pẹ̀lú awọn ènìyàn rẹ̀. O ti se adehun ọsẹ-ọsẹ yìí pẹlu rẹ. Mase kunna lati maa pade Rẹ̀.

**4.** Báwo ni Ọlọrun se fi pàtàkì Ọjọ Isinmi Mímọ́ Rẹ̀ hàn?
**Eksodu 20:8-11**
Rántí ọjọisinmi, láti _______ sí mímọ́, Ọjọ mẹ́fà ni iwọ o sisẹ, tí iwọ o sì ṣe iṣẹ́ rẹ gbogbo: sùgbọ́n ọjọ́ keje li ijọ isinmi OLUWA Ọlọrun rẹ: nínú iwọ kò gbọdọ̀ ṣe isẹkisẹ kan, iwọ, ati ọmọ rẹ okunrin, ati ọmọ rẹ obinrin, ọmọ-ọ̀dọ̀ rẹ okunrin, ati ọmọ-ọ̀dọ̀ rẹ obinrin, ati ohunọṣin rẹ, ati àlejò rẹ tí mbẹ ninu ibodè rẹ: Nitori ni ijọ mẹfa li OLUWA da ọrun oun aye, òkun ati ohun gbogbo ti mbẹ nínú wọn, o si sinmi ni ijọ keje, nitori náà li OLUWA se ______ ijọ keje o sì yà á sí mímọ́.

Àkíyèsí: Eksodu 20:8-11 je aṣẹ kẹrin òfin Ọlọrun. Nipa wípé O fi ọjọ isinmi ṣe ọkan ninu awọn òfin mẹwa, O fi pàtàkì rẹ han. Ẹṣẹ kẹwa pè é ni ‘ọjọ isinmi Oluwa Ọlọrun rẹ.’ Òfin kẹrin nikan lo bẹ̀rẹ̀ pẹlu ‘rántí’, èyí ti o n fi han wípé Ọlọrun ti mọ̀ pé awọn ènìyàn yíò gbàgbé. Rírú ọkan nínú òfin mẹwa jẹ ẹ̀ṣẹ̀ (1 Johannu 3:4). Sùgbọ́n Jesu kú kí O le gba awọn ènìyàn Rẹ là kuro ninu ẹ̀ṣẹ̀, tàbí kúrò lọwọ rírú òfin. (Matteu 1 :21)





**5.** Laarin ohun tó ṣe iyebiye meji wo ni Ọlọrun ti wípé Ọjọ Isinmi jẹ́ àmì?
**Eksodu 31:17**
Àmì ni iṣe laarin èmi ati laarin awọn ọmọ Israeli títí láí: nitori ni ijọ mẹfa li _________ ______ ọrun oun ayé, ni ijọ keje o si sinmi, o ṣi se ìtura.
**Esekieli 20:12**
Pẹ̀lúpẹ̀lú mo si fun wọn ni ọjọ isinmi mi, lati se àmì laarin t’emi ti wọn, kí nwọn kí o le mọ̀ pe emi ni OLUWA tí o ______ wọn sí ______.

Àkíyèsí: Ọlọrun sọ wípé ọjọ isinmi jẹ àmì, ìlà agbara Rẹ̀ gẹ́gẹ́ bi Ẹlẹda tabi Olùràpadà. Ninu Ifihan 14:6-14, Ọlọrun fun wa ọ̀rọ̀ pàtàkì mẹta lati sọ fun "awọn to n gbé orí ilẹ ayé, ati fun gbogbo orílẹ̀, ati ẹ̀yà, ati èdè, ati ènìyàn." Ẹṣẹ ikẹfà. Ọ̀rọ̀ akọ́kọ́ wa ni ẹṣe keje: "O nwí li ohùn rara pé, Ẹ bẹ̀rù Ọlọrun, kí ẹ si fi ogo fun un; nitori ti wakati idajọ rẹ̀ dé: ẹ si foribalẹ fun ẹniti o dá ọrun, oun ayé, ati okun, ati awọn orisun omi." Ìyànjú lati pada si inú ìsìn otitọ ni a yọ jade lati inu òfin kẹrin: "Nitori ni ijọ́ mẹfa li OLUWA dá ọrun oun ayé, òkun ati ohun gbogbo ti mbẹ wọn, o si sinmi ni ijọ́ keje." Eksodu 20:11.

**6.** Ọjọ wo ni Jesu pa mọ́?
**Luku 4:16**
O sì wá sí Nasareti, nibiti a gbe ti tọ ọ dàgbà: bí ______ rẹ ti rí, o sì wọ inu sinagogu lọ li ọjọ isinmi, o sì dide lati kàwé.

Àkíyèsí: Jesu ni àwòkọse wa (1Peteru 2:21) nínú ohun gbogbo, iba se pípa ọjọ́ isinmi mọ́, èyí to jẹ àsà Rẹ̀. "Àsà" jẹ́ ìwà ti ko le e yẹ̀. Kristiani gbọ́dọ̀ rìn gẹ́gẹ́ bo se rìn. (1 Johannu 2:6).

**7.** Kinni àsà Paulu niti Ọjọ́ Isinmi
**Ise Awọn Aposteli 17:2**
Ati Paulu, gẹ́gẹ́bí _________ _______, o wọle tọ wọn lọ, li ọjọ isinmi mẹta o si mba wọn fi ọ̀rọ̀ we ọ̀rọ̀ nínú ìwé-mímọ́
**Ise Awọn Aposteli 18:4**
O si nfọ̀rọ̀ we ọ̀rọ̀ fun wọn ninu sinagogu ni _________ _________, o si nyi awọn Ju ati awọn Helleni li ọkàn padà.

Àkíyèsí: O tun jẹ́ àsà Paulu lati maa pa ọjọ keje Isinmi mọ́.

**8.** Njẹ́ awọn aposteli bá awọn Keferi pàde ni ọjọ Isinmi?
**Ise Awọn Aposteli 13:42**
Bi nwọn si ti njade, (awọn ________) bẹ̀bẹ̀ pé kí a sọ̀rọ̀ wọnyi fun wọn li ____________ ti mbọ̀.

Àkíyèsí: Ni ìgbà miran, awọn ọmọ lẹhin ba awọn obinrin Keferi pàdé ni ẹ̀gbẹ́ odò ni ọjọ isinmi miran, nitori ti wọn kò ni sinagogu (Ise Awon Aposteli 16:13).

**9.** Njẹ́ Jesu fẹ́ ki awọn eniyàn rẹ̀ maa pa ọjọ isinmi mọ́ lẹhin tí o ti kú nitori ẹ̀sẹ̀ wọn?
**Matteu 24:20**
Ẹ sì maa gbadúrà ki sisa nyin kí o mase jẹ́ ìgbà otútù, tàbí ọjọ́ ________.

Àkíyèsí: Jesu nsọ isubu Jerusalẹmu èyí ti yíò sẹlẹ lẹhin ikú rẹ̀ A.D. 70 (bi iwọn ogoji ọdun lẹhin ikú rẹ̀). Sùgbọ́n, o rò o wípé ki akoko sisa wọn lọ́wọ́ awọn ologun ko ma jẹ ọjọ isinmi. Èyí hàn dájú pé, Jesu fẹ́ ki awọn eniyan máa pa ọjọ isinmi mọ́ lẹhin ti O ba ti kú tán.

**10.** Se Bibeli sọ fun wa wípe awọn eniyan ìgbà ikẹhin yíò ma pa ijọ keje ọjọ́ isinmi mọ́?
**Ifihan 12:17**
Dragoni náà (eṣu) sì bínú gidigidi sí obinrin náà ( ijọ tabi ṣọọsì), o si lọ ba awọn irú-ọmọ rẹ̀ ìyókù( tí wọn ṣẹkù) jagun, ti nwọn ________ ________ Ọlọrun mọ́, ti nwọn sì di ẹri Jesu Kristi mú.
**Ifihan 14:12**
Nihin ni sùúrù awọn ènìyàn mímọ́ gbé wà, awọn ti ________ ________ Ọlọrun ati ìgbàgbọ́ Jesu mọ́.
**Ifihan 22:14**
Ìbùkún ni fún awọn ti ________ òfin rẹ̀ mọ́, ki nwọn ki o le ni ànfàní lati wá sí ibi igi ìyè náà, ati kí nwọn kí o le gba awọn ẹnubode wọ inu ìlú náà.

Àkíyèsí: Ó hàn gbangba wípé ẹṣe Bibeli òkè yìí nsọ̀rọ̀ nipa awọn Ijọ Ọlọrun ti ìgbà ikẹ̀hìn, ati wípé ẹṣe kọọkan nse àlàyé gbangba pé ijọ Ọlọrun ti ìgbà ikẹhin npa òfin Rẹ̀ mọ́, tí o si jẹ wípé òfin kẹrin wà nibẹ, Ọjọ Isinmi.

**11.** Njẹ awọn ti a gbàlà ni ọrin yíò ma pa Ọjọ Isinmi mọ́?
**Isaiah 66:22,23**
Nitori gẹ́gẹ́ bí awọn ọrun titun, ati aye titun, tí emi o ṣe, yíò ma dúró niwaju mi, bẹ̀ẹni iru-ọmọ rẹ ati orukọ rẹ yíò dúró, li OLUWA wí, Yíò si ṣe, gbogbo ________ yíò sì wa ________ niwaju mi, lati osù titun de osù titun, ati lati ọjọ isinmi dé ọjọ isinmi, li OLUWA wí.

Àkíyèsí: Bibeli sọ fun wa wípé gbogbo awọn ẹni irapadà gbogbo ni yíò pa ọjọ isinmi Ọlọrun mọ́ papọ ni ọrun titun ati aye titun.

**12.** Ṣe a le ri aridájú wípé ọjọ isinmi ọsẹ ti isinsinyi **(Satide)** ni ọjọ isinmi ti Jesu pẹ̀lú pa mọ́ bí?
**Luku 23:54-24:1**
O si ṣe ọjọ ìpalẹ̀mọ́, ọjọ́ isinmi sì kù sí dẹ̀dẹ̀, Ari awọn obinrin, tí nwọn ba a ti Galili wa, ti nwọn si tẹle, nwọn kiyesi iboji náà, ati bi a ti tẹ òkú rẹ si, Nigbati nwọn sì padà, nwọn pèsè ohun oloorun didun ororo ikunra ati tùrárí tutù; nwọn si ________ li ọjọ________ gẹ́gẹ́ bi ofin, Ni ________ ________ ọ̀sẹ̀, ni kùtùkùtù òwúrọ̀, nwọn wá sí iboji, nwọn nmu turari wa ti nwọn ti pèsè sílẹ̀, ati awọn miran kan pẹlu wọn.

Àkíyèsí: A kan Jesu mọ́gi ni ọjọ Jímọ̀ (ọjọ ipalẹmọ), ọjọ tí o síwájú ọjọ isinmi (Marku 15:42) Jesu sinmi nínú iboji ni ọjọ isinmi ti òfin (Luku 23:56), o sì jí dìde ni ọjọ kinni - ọjọ tó tẹle Ọjọ Isinmi (Marku 16:1-6). Awọn Kristiani ní àgbáyé nse ayẹyẹ ọjọ náà gẹgẹ bi ọjọ Isinmi Ọ̀pẹ. O rọrun pipọ̀ lati ri ọjọ náà ninu ọsẹ ninu Kalẹnda. (Wo àfikún "Ohun ti Dikisanari sọ" ati wipe "A ko yi Kalẹnda pada")



**13.** Se Ọlọrun gbà ki ẹnikẹni yí ọjọ mímọ́ Rẹ̀ padà?
**Owe 30:5,6**
Gbogbo ọ̀rọ̀ Ọlọrun jẹ́ òtítọ́: oun li aṣà fún gbogbo awọn tí o ________ wọn le e, Ìwọ mase fi ________ ọ̀rọ̀ rẹ̀, ki oun ma ba ba ọ wi, a si mu ọ li èké.

Àkíyèsí: Kí ó tó di wípé Ọlọrun gbé òfin mẹwa kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bi a ti se àpèjuwe rẹ̀ nínú ìwé Deuteronomi orí karun (5), O sọ pẹlu ìrẹ̀lẹ̀ wípé ẹnikẹni kò gbọdọ "fi kún" tàbí "yọ kúrò" ninu wọn (Deuteronomi 4:2). Nitori náà, wọn gbọ́dọ̀ pa wọn mọ́ gẹ́gẹ́ bí O ṣe fi fun wọn. Ọlọrun ya Ọjọ Isinmi Rẹ̀ sí mímọ́ (Eksodu 20:11), ati wípé bí Ọlọrun ba ya nkan kan sí mímọ́, a ṣe wípé, O ti ya si mímọ́ títí ayérayé (1 Kronika 17:27). Ọlọrun tilẹ̀ sọ wípé "Majẹ̀mú mi ni emi kì yio dà, bẹ̀ẹ̀li emi kì yíò yí ohun ti o ti ètè mi jade pada." Orin Dafidi 89:34. Àwọn to ti sìnà sọ wípé Ọjọ Isinmi mímọ́ Ọlọrun ti yipada si ọjọ Àìkú (Sunday). Sùgbọ́n kò se ṣe kí Ọlọrun gba ẹ̀kọ́ ènìyàn nígbàtí O ti fi Bibeli fún wa gẹ́gẹ̀ bi amọ̀nà.

**14.** Ìgbà wo ni Ọjọ Isinmi nbẹ̀rẹ̀ ti o si ma n parí?
**Lefitiku 23 :32**
___________ ni fun nyin, kí ẹnyin kí o sì pọ́n ọkàn nyin lọ́jú: li ọjọ kẹsan osu náà li alẹ, ni ki ẹnyin kí o ma _______ ọjọ-isinmi nyin mọ́.
**Marku 1:32**
Nígàtí o di aṣalẹ, tí ________ wọ, nwọn gbe gbogbo awọn ________, ati awọn ti o lí ẹmí esu tọ ọ wa.

Àkíyèsí: Ọjọ Isinmi bẹ̀rẹ̀ ni ìrọ̀lẹ́ ti òòrùn ba ti wọ̀ ni ọjọ Jimọ (Friday) títí di ìgbà ti òòrun ba wọ̀ ni ọjọ Satide (Saturday).

**15.** Ọjọ wo ni ọjọ Oluwa ti Ifihan 1:10?
**Eksodu 20:10**
Sùgbọ́n ọjọ keje li ijọ́ isinmi ________ Ọlọrun rẹ: nínú rẹ̀ ìwọ kò gbọdọ̀ ṣe iṣẹ́kíṣẹ́ kan, ìwọ, ati ọmọ rẹ ọkunrin, ati ọmọ rẹ obinrin, ọmọ-ọdọ rẹ ọkunrin, ati ọmọ-ọdọ rẹ obinrin, ati ohunọsin rẹ, ati alejò rẹ ti mbẹ ninu ibodè rẹ.
**Isaiah 58:13**
Bí ìwọ ba yí ẹsẹ̀ rẹ kúro li ọjọ isinmi, lati ma ṣe afẹ́ rẹ li ọjọ________ mi; tí ìwọ si pe ọjọ isinmi ni ________, ọjọ mímọ́ OLUWA, ọlọ́wọ̀; tí iwọ si ________ fun un, tí iwọ kò hu ìwà rẹ, tabi tẹle afẹ rẹ, tabi sọ ọ̀rọ̀ ara rẹ.
**Marku 2:28**
Nitori náà Ọmọ-eniyan li Oluwa ọjọ isinmi pẹlu.

Àkíyèsí: Ninu Majẹmu lailai ati Majẹmu titun ni Ọlọrun ti pe ọjọ isinmi ni ọjọ Oluwa. O si tun paṣe lati kilọ̀ fun awọn ènìyàn ki wọn kiyesara kí wọn ma ṣe maa dẹ́sẹ̀ nipa pe wọn ko pa ọjọ isinmi mọ́. (Isaiah 58:13). Ọlọrun wípé Ọjọ Isinmi Mímọ́ Oun wà fun gbogbo ènìyàn (Isaiah 56:2-7). Bibeli ko fi ìgbà kankan sọ wípé ọjọ Àìkún (Sunday) ni ọjọ Oluwa. Sunday jẹ́ ọ̀kan ninu awọn ọjọ mẹfa ti a fi nsiṣẹ́ ni aarin ọsẹ (Ezekieli 46:1).



**16.** Kini ìbùkún ti a lérí niti òfin Ọjọ Isinmi
**Matteu 11:28**
Ẹ wa sọdọ mi, gbogbo ẹnyin ti nsíṣẹ, tí a sì di ẹrù wuwo lé lórí, emi o si fi ________ fun nyin.
**Eksodu 33:14**
Oun sì wípé, ________ mi yíò ma ba ọ lọ emi o si fun ọ ni isinmi.
**Heberu 4:5**
Ati nihinyi ẹ̀wẹ̀ pe, Nwọn ki yio wọ________ ________ mi.

Àkíyèsí: Gbogbo òfin mẹwa ni ẹyọ kọọkan ni wọn ni itumọ ti ẹmí tiwọn, sùgbọ́n awọn kan ninu onígbàgbọ́ ti òde òní ni wọn gbójú le bi a ṣe kọ awọn òfin náà sílẹ̀ ti wọn si gboju fo itumọ̀ ti ẹmi ti awọn ofin náà ni. Jesu fẹ́ kí a ni ìmọ̀ mejeeji ki a si ṣe wọn ni ọ̀nà kan náà (Matteu 5:21,27,28). Bibeli ma nlo "isinmi" gẹ́gẹ́ bi ìgbàlà. Heberu 4:1,4,9,10 sọ wípé awọn tó ti mu wọ inu "isinmi" ti irapadà ti wọn si ngbé inú Kristi yio ma pa ọjọ keje ọjọ isinmi mọ́ bi apẹẹrẹ Ọjọ Isinmi Kristiani.

# Èsì Rẹ

Gẹ́gẹ́ bi Jesu ṣe fun wa ni Ọjọ Isinmi gẹ́gẹ́ bi agbara Rẹ̀ ti o fi dá ohun gbogbo ti o sì yá à sí mímọ́, ṣe iwọ náà fẹ́ lati ma a gba ìbùkún tó wà ninu pipa Ọjọ Isinmi mọ́ lati fi yẹ ẹ (Jesu) sí.

ÌDÁHÙN:______________________

# Àfikún

Ipele yìí yio fun wa ni awọn ọ̀rọ̀ afikun lati tun kẹkọ síwájú.

Kini Dikisonari sọ
Wá awọn ọ̀rọ̀ wọnyi ninu Dikisonari to wu ọ, ki o si wo ohun ti wọn sọ nipa wọn: Satide **(**ọ̀rọ̀-ajorukọ**)** - ọjọ́ tó gbẹhin ninu ọ̀sẹ, ọjọ keje Ọ́ẹ̀yan ajorukọỌ̀ ti ọjọ keje (Satide). Àìkú **(**Sunday**)** **(**ọ̀rọ̀-ajorukọ**)** - Ọjọ kini ninu ọ̀sẹ̀. Ọjọ kini **(**ọ̀rọ̀-ajorukọ**)** - Àìkú (Sunday)

Se wọn kò yí kalẹnda pada rí?
A yi kalẹnda pada lẹẹkan ni osù kẹwa ọdun 1582, sùgbọ́n bi kalẹnda se yípadà yìí, ko yi bi ọjọ se n yí padà. Ọjọ mẹwa ni a fo tabi yọ kurò ninu kalẹnda ọdun náà lẹhin ọjọ kẹrin (4) ọdun 1582. Jimọ (Friday) ọjọ karun (5) di Jimọ (Friday) ọjọ karundinlogun (15). Àwọ̀rán tí o wa nisalẹ yìí yio ran ọ lọ́wọ́ lati ri ohun to sẹlẹ̀, wa tilẹ tun ri wípé kò yi bi ọjọ se tò tẹle ara wọn pada.

Osù kẹwa **(OCTOBER)** 1582

| Sun. | Mon. | Tue. | Wed. | Thu. | Fri. | Sat. |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | 1 | 2 | 3 | 4 | 15 | 16 |
| 17 | 18 | 19 | 20 | 21 | 22 | 23 |
| 24 | 25 | 26 | 27 | 28 | 29 | 30 |
| 31 | | | | | | |

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP7.indd 2 12/6/12 11:44 AM